# Ó di gbéré, ó di kése, Adébayọ̀ Fálétí

Lere Adeyemi
Department of Linguistics and Nigerian Languages
University of Ilorin
Nigeria
adeyemiolalere@yahoo.com

Bínú bá ń bífá,
Ọmọ aráyé á fewúrẹ́ dúdú bọfá;
Bínú ọ̀pẹ̀lẹ̀ ò dùn,
Ọmọ aráyé a f`àgùtàn bọ̀lọ̀jọ̀ ṣètùtù;
Orógbó pẹ̀lóbì lẹbọ Ṣàngó
Bí Lakáayé ń bínú,
Aráyé a fún un lájá jẹ.
Ikú kọ̀, ikú kò gbẹbọ.
Ṣé bíkú bá jẹja láyé ijọ́sí,
Ọwọ́ ikú a máa gbọ̀n irórò irórò,
Bíkú bá jeku nígbà ìwáṣẹ̀,
Ẹsẹ̀ rẹ̀ a máa gbọ̀n irìrì irìrì,
Bíkú bá jẹyin ẹlẹ́butẹ, ara ikú a máa já ibùtẹ̀ ibùtẹ̀,
Ikú àsìkò yìí bàjẹ́ kò gbẹbọ kò gbètùtù,
Ìkà nikú, ikú kò màgbà bẹ́ẹ̀ ni kò mọmọdé,
Bílé oyin bá kan gbínrín gbínrín,
Bẹ́ẹ̀ wádìí rẹ̀ wò, iṣẹ́ ikú ni,
Bọ́dẹ̀dẹ̀ `adò bá sì dibi ikorò,
Ikú ló fa sábàbí ẹ̀.

Ikú pagbe bí ẹni tí ò dáró,
Ikú pàlùkò bí ẹni tí ò kosùn,
Ikú pa lékèélékèé bí ẹni tí ò kẹfun,
Ikú ọ̀hún ló pa Adébáyọ̀ ọmọ Fálétí,
Bí ẹni pé Ifá ò létí,

Ikú pàkọ̀kọ́ ó fomi akọ̀kọ́ ṣòfò!
Lọ́jọ́ mo gbọ́kú ọmọ Fálétí,
Tí mo jí láfẹ̀mọ́júmọ́ kóri ìdájí ó tó tó dá,
Mo bojú wapá mi ọ̀tún, gbogbo ìlú dákẹ́ ṣíriṣíri,
Gbogbo igbó pa kánrin kése,
Ọmọdé ilé, wọn ò lè sọkún ọmú,
Ẹní jókòó, wọn ò lè dìde,
Ẹní tó nàró, kò lè bẹ̀rẹ̀,
Kowéè kan wá ǹ ké líle líle,
Kò sí ẹ̀rọ̀ pẹ̀ṣẹ̀ lóhùn ẹyẹ awo,
Àṣé ọmọ Ọ̀yìnyìn a-tàn-bí-wúrà,
Ọmọ Fálétí ló lọ gbèkuru jẹ lọ́wọ́ ẹbọra,
Aṣe ẹni mo rò pé kò lè kú lógún ọdún síbí,
Aṣe agbáṣàga ti mo rò pé kò lè papòdà lọ́gbọ̀n oṣù,
Pé yóò sìn wá dẹ́sẹ̀ omi,
Lomi ikú ti wọ́ lọ sálákeji,
Ìràwọ̀ àgbà ti jáludò, kò leè tàn mọ́,
Ò tẹ̀rókò ìmọ̀ fidà rọ̀, ó ti lọ,
Òkéké! A-rẹnu-ké-ọ̀ràn-bí-ọ̀bẹ, ó ti lọ,
Àtàtà òǹkọ̀wé, afínjú akéwì tí ń fewì sọ̀tàn,
Ọmọ Ìdọ́dẹ, Pàràkòyí ọmọ Ọ̀yọ́ Aláàfin, ó ti lọ
Bí Adébáyọ̀ Fáléti ti pẹ́ tó láyé,
Tó dàgbà darúgbó kàngẹ́kàngẹ́,
Sibẹ̀, lọ́jọ́ ti baba relé,
Ajá kọ̀, ajá ò gbeegun,
Adìyẹ rọ́kà, wọn ò yọ ṣẹ̀ṣẹ̀
Gbogbo ọmọ Yọrùbá ló ń ṣèdárò akọni
Àwọn òṣèré ń ṣe ìdárò akọni,
Ẹgbẹ́ akéwì, ẹgbẹ́ sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀ ń ṣedárò akọni,
Ẹgbẹ́ onímọ̀ Yorùbá ń ṣèdárò ẹni rere
Gbogbo ọba Yorùbá ló ń mìrùkẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀dùn ọkàn
Nígbà tó wà láyé, bí baba tì ǹ gbọ́ tẹrú
Ní baba ǹ gbọ́ tọmọ,
Ó gbọ́ ti Tápà léǹpe, ó gbọ́ tabokí
Ó gbọ́ ti Yánmírín, ó fi eré fíìmù gbọ́ tiwọn lájìndò Gúsù
Òkìtì gbogbo kọ́ ní hu olú ọgán
Gbogbo ọmọ olóyè kọ́ ní róyè ọba jẹ,
Onífìlà àgọgọ̀ joyè ìmọ̀, ó fi ṣe gbogbo ayé lóore
Àwọn eré, àwọn orin àti ìtàn-àròsọ rẹ̀
Ló jẹ́ ajómọ-lẹ́sẹ̀-bí-ìpìn!
Gbogbo àrokò rè nínú eré fíìmù Àfọ̀njá

Kí Yorùbá ó lè dọ̀kan ṣoṣo
Kí ìran Odùduwà, tó jọ́mọ alátẹ ìlẹ̀kẹ̀,
Kó má dọmọ alátẹ ọ̀rúnlá tí ń bá àbókí gbẹ́ kànga
Kó tó ṣe rere nílẹ̀ Nàìjá.

Ẹní tó magbe, kò bá ní dárò aró,
Ẹní tó màlùkò kò bá ní dàrò osùn
Ẹní tó mọ lélèélékèé kò bá ni dárò ẹfun
Ẹní tò bá mọyì àgbà,
Kó bá ní dárò akọni.
Atóófọjọ́mọ, Alágbẹ̀dẹ èdè
Àgbà òpìtàn, arótàn bí ọ̀pẹ̀lẹ̀
Erin gùnkè àlọ̀, ẹran lọ Àkẹ́ẹ̀!
Ògìdán ò pè méjì níjù
Háà! Ọ̀kẹ́rẹ́ gorí ìrókò
Ojú ọdẹ dá!
Ọmọ Yorùbá ẹ kú ìdárò akọni.

Ó tọ́, ó sì yẹ kí ń sọ gínńgín lórí iṣẹ́ tí baba ṣe
Kí baba ó tó dágbére fáyé
Bí a bá pérí akọni, à fidà lalẹ̀
Bí ò bá sí iṣu kí la ó gún níyán?
Bí ò bá sí èlùbọ́ kí la ó rò lọ́kà?
Bí ò bá ságbàdo, ẹ̀ẹ̀rùn,
Kí la ó rò lẹ́kọ yangan
Ọ̀pẹlọpẹ, ọmọ Fálétí afìtànkọ́mọ-níwà-Oòdáyé
Kínńkín ní à bà mọ nítàn ìṣẹ̀dálè Ọyọ́,
Bí kò sí ere-onítàn, ìtàn-àròsọ àti ewì tó fi pàrokò
Ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ Ọ̀yọ́ ìbá ṣàjèjì sí ìran òde òní
Ọpẹ́lọpẹ́ òpìtàn, òǹkọ̀tàn, aròtàn tó morírun Ọ̀yọ́,
Ó mọ̀tàn Ifẹ̀, ó tún mọ tèkìtì òkè
Ọjọ́ tọ́mọdé bá kọyán àná,
Àwọn àgbà a fìtàn balẹ̀,
Ọjọ́ ò tò jọ́jọ́, ọjọ́ ò tọ́jọ̀
Tógun ajunilọ dó sílẹ̀ Kòkànmí
Ìmúnisìn ilé, ìmúnisìn oko,
Ogun ajunilọ dó sílẹ̀ Oòduà,
Ọmọdé ilé kò rójú,
Àwọn àgbà kùjọ́kùjọ́ ibẹ̀ kò ràyè,
Wọn gbèdè lẹ́nu elédè wọ́n gbàrùkẹ̀rẹ̀ lówọ́ ọba wọn,
Babaláwo pe fá títí, ifá ò gbọ́,

Oníṣègùn pọ̀pẹ̀lẹ̀ títí, ọ̀pẹ̀lẹ̀ ò gbẹbẹ̀,
Onígbàgbọ́ pẹ́ nílé olúwà bí kọ́bọ̀ àkọ́dé,
Àwọn mùsùlùmí pẹ lọ́ọ̀dè Ànábì bí tọ̀yọ́bọ̀,
Gbogbo akọni ló tí dẹrú alágbára
Àfòpìtàn tó gbédè bí òfé ló lérò tọ yàtọ̀
Ọlọ́gbọ́n-inú- Ọ̀yọ́ kéré jọ nílùú Ọ̀yọ́
Ó ṣeré Sùúrù àti ọgbọ́n pé kí kálukú ó fọgbọ́n ṣe
Eré yìí gbayì, ó gbẹ̀yẹ, ó tún fálágbára ní sùúrù.

Ìwé ìtàn-àròsọ Ọmọ Olókùn Ẹsin ló tú àṣírí àwọn alágbára
Kó tó di pé àwọn alágbára ilé àti toko fi sinmẹ̀dọ̀
Alágbára lọ, ṣúgbón kò bá wọn wá kì í ba wọn lọ
Àṣà àtiṣe Yorùbá tún rẹ́ṣẹ̀ walẹ̀.
Lẹ́yìn òmìnira ń kọ́? ọmọ Fálétí ṣe bẹbẹ
Ó kọ̀wé, ó kọ̀tàn, ó tun kọrin tó lárinrin fómìnira
Ó kọ̀wé kan ó pè é ní Ogun Àwítẹ́lẹ̀
Ogun àwítẹ́lẹ̀ tí kì í parọ tó bá gbọ́n,
Ogun olè, ogun ajọ́mọgbé bẹ̀rẹ̀ ní ràbájìgan
Ẹní ǹ rogun ojúgbo,
Kó máà jorógbó onígbó
Ẹní bá togun dé ní wọn ǹ kí kú oríire
Ẹni tàjò dé ní wọn ǹ kí 'ẹ̀ kí ewu ọ̀nà'
Fálétí pàrokò títí, ogun àwítẹ́lẹ̀ kọ̀ kò lọ,
Agbódórogun kò sì padà bọ̀.

Bí ṣe ǹ kọrin, ló ǹ kéwì ló tún ń kọ̀wé,
Lẹ́yìn òmìnira Nàìjíríà ni ìnira tuntun wọlé dé,
Gbẹgẹdẹ tún gbiná si,
Lòmìnira fimú ẹlẹ́dẹ̀ gùn dọ́gbà,
Làwọn olóṣèlú gbàbọ̀dì,
Àbẹ̀tẹ́lẹ̀ wọ̀lú, ló bá dolórúkọ gídi,
Owó ẹ̀yìn wá dọmọ onílẹ̀ lọ́dọ̀ wa,
Ló wa dolórúkọ ńlá,
Òun náà ní wọn ǹ pé ní rìbá,
Sọwọ́kúdúrú wá ǹ ṣebí láàárín wa,
Fálétí ké ké ké,
Ó yán yán yán,
Kí ìwà olè àti rìbá ó le dẹ́kun láàárín ìlú,
Ó dẹ́gbé eléré Alébíoṣù sílẹ̀,
Ó ǹ ṣere Ṣawoṣọ̀gbẹ̀rì,
Ó ṣeré Fẹrẹ bí ẹkùn lórí amóhùnmáwòrán

Bóyá, aráyé a ṣíwọ́ iṣẹ́ íbí ṣíṣe
Àwọn aláágànná ẹ̀dá
Àwọn asínwín ayé gbogbo kọ̀ wọn ò gbọ́
Wọ́n ń purọ́ wọ́n ń tan aráyé jẹ kiri
Wọn lówó borí ọmọ ni wọ́n ń hùwà ẹranko kiri,
Gbogbo wọn ló ń kówó ìlú jẹ bí ẹni jẹṣu,
Fálétí kéwì lórí rédíò ló tún dọ̀ràn.
Ṣé tibitire ló ǹ rìn pọ̀ láyé ọmọ ènìyàn,
Kì í dùn, kó má kan,
Kì í sì kan, kó má dùn,
Bí ènìyàn ò fẹnu kan ìbó wò,
Kò ní mọyì oyin lẹnu,
Ìṣèdálẹ̀ ayé ni,
Lọmọ aráyé ń fọmọ wọn ṣẹ́só,
Ènìyàn gidi ń ṣe bí wèrè lọ́jà ọba,
Aráyé rò pé wèrè gidi ni,
Ni Fálétí fi kọ Nwọn rò pé Were ni,
Wèrè gidi kọ wérewère ni o jàre.

Nigbà tó bùṣe gàdà, tó bùṣe gèdé,
Làwọn ṣọ́jà tún gbòde,
Fálétí tún gbéré Ìjà Orogún dórí àtẹ,
Ní ṣójà àtolóṣèlú ǹ yíra wọn sébè,
Wọn ǹ yira wọn sáporo oko,
Ṣójà dé, òbúkọ dé, òórùn dé, ìjàǹbá wọ̀lú,
Olórí ọlọ́ṣà wá ǹ sọ ìgboro,
Bẹ́ẹ̀ ní ìjà ẹlẹ́yàmẹyà, ìjà ẹ̀ṣìn ṣe bẹ́ẹ̀ tó wòlú,
Ó wọ̀lú wẹ́rẹ́ ni ẹ̀sìn ń dààmú ẹlẹ́sìn,
Ìdààmú páádì Míǹkáǹlù ló fèyí han.

Gbogbo ìdààmú ìlú tó farahàn ninú ìlú,
Lọmọ Fálétí wọ́nà àbáyọ fún nínú ìwé rẹ̀,
Ẹ ka Àṣà Agúnbẹ nínú `Awòrérìn,
Ẹ ka Àgbàlagbà já lórí igi,
Ṣebí káyé ó lè dára fún wa ni.

Adébáyọ̀ Fálétí ṣe bẹbẹ fun ìran ènìyàn,
Nígbà ti ìlú fẹ́rẹ̀ẹ́ fọ́ mọ́ olórí ilẹ̀ yìí kan lórí,
Ọ̀gàgun náà gbóná ó ju iná lọ,
Ṣé iná kan ì í gbóná, kó gbóná tewétewé,
Yèèsì kan ò sì gbóná, kó gbóná tegbọ̀tegbò,

Ataare kì í gbóná, kó gbóná tèèpo tèèpo,
Ìwà èèpè tó mulẹ níkùn alágbára tí à ń wí,
Ó pọ̀ ju iwa rere lọ,
Ìwà ìkà ló gbé wọ̀ bí ẹ̀wù,
Káráyé ó lè rọ́gbọ́n kọ́,
Ní Fálétí fí gbéré Baṣọ̀run Gáà tó ti kọ lọ́jọ́ pipe,
Jáde sórí fíìmù àgbéléwò, bóyá àyípadà yóò dé báwùjọ wa,
Ẹni tó bá ka ewì baba nínú Ewì Ìwòyí,
Yóò mọ̀ pé ẹran ki sẹ́sẹ̀ ràgó.

Ọlọ́gbọ́n ilé Ọ̀yọ́, ọmọ Fálétí ti lọbi àgbà rè,
Ike dá, owó iké gbé,
Sèsé là, ó là dànù,
Ọ̀páláńbá ọtí èèbó fọ́, onígbǹsọ kò rí i sọ,
Odó iyán dodó ẹ̀lú, baba wa ti lọ.
Bí o bá délé, o kílé, bí o dọ́nà, o kérò ọ̀nà
Ẹ bá mi kí baba mi tó ti ń bárá ọ̀run jẹ lọ́jọ́ pípẹ́
Ọmọ ọlọ́lá joyè méjì pọ̀,
Ọmọ ọ̀yẹ̀ kẹ́kẹ́ oníbàrá òjé,
Ẹ bá mi kí ìyá mi, Aríbakẹ́ Ìbídọjà ọmọ akọ́léiyán,
Onísùúrù ló lè fún wàrà kìnnìún,
Ẹ bá mi kí àwọn àgbà ọ̀jẹ̀ bí Olóyè Oludare Ọlájubù,
Ẹ jíṣẹ́ mi fún baba Afọlábi Ọlabimtan, Orílawẹ̀ Àdìgún,
Orí la wẹ̀ a ò wẹ̀ṣẹ kànìnkànìn la wẹ̀, a ò wẹjìnrìn,
Ẹ bá mi kí Páàdì Ilésanmí, tó ti débi ìsinmi,
Ẹ má gbàgbé àwọn akọni ọmọ Yorùbá yòókù pátá,
Tí wọ́n ń bẹ lájùlé ọ̀run,
Ọmọ Fálétí, ó di gbéré,
Ó di kése, ó dàrìnàkò, ó dojú àlá,
Ó tún dọjọ́ mìíràn ká t'o túnra rí,
Ìpàdé dọjọ́ àjíǹde lẹ́sẹ̀ Olùgbàlà!

